# JAMBA SELE NINU OKO RELUWE NI LALUPON







ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI-L'EJO








VOL. IX No. 540. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, OCTOBER 5, 1957. KỌBỌ MEJI (2)


## Ojojo Ns'ogun



### Ara Ogun Kole

Aworan ọmọ'ba ọkunrin ti nwọn npe ni Prince Charles ni a nwo yi; on ni a gbọ wipe amodi ayọkẹlẹ (Influenza) f'araba.

Amodi ko mọ ọba, beni ko mọ ẹni-ọwọ, bi o ti nṣe olowo, bẹni o nṣe talaka, ogboju Onişegun papa nṣe amodi.

Jọwọ Şali ẹni-ọla, maşe amodi, Oluwa yio wọ ọ.

---

### Ojo Isimi (holiday)

Ni Monday ọtunla ọjọ 7th oşu October 1957, ni ọjọ ti ao şe iranti ọjọ ibi Anobi Mohamed (S.A W.S) Ẹnikẹni ko ni şişẹ lọjọ na faaji ati isimi yio wa kakiri ilẹ Musulumi.

## Jamba Sele Ninu Oko Reluwe



Okan ninu awon ti jamba Oko Reluwe se ti nwon ri yo jade ni awon Olopa gbe sinu Agbala (Stretcher) ti nwon ngbe lo ni a nwo ninu aworan oke yi.

Awon e ia ti a gbo wipe nwon ti ri gbe ti o je oku nlo si adorin enia ati wipe ko si ireti mo fun pe nwon tun le ri enia kan l'aye ninu Wagonu meji ti o ku, eyikeyi ti nwon ba tun ri nisisiyi, nwon yio ma gbe sinu Posi, nwon o si ma sinku won si eti odo ti jamba na ti sele

Ki Olorun ma je k'a rin lojo ti ebi np'ona.

---

### Akiyesi Pataki Fun Awon Asoju Eleti-Ofe

A fi eyi se ikede fun ẹnyin Aşoju ati Oluta Iwe Irohin wa Eleti-Ọfẹ wipe ẹnikẹni ti ko ba fi owo Iwe Irohin ranşẹ si wa ki o şu yi to pari, ao fi orukọ re fun Lọya Eleti-Ọfe lati pe lejọ, ao si gba Owo irin ẹşẹ lọwọ rẹ.

Ọlọtu

### Aloo! Alo

Rukuruku yekete, Rukuruku yekete eniti o ru oku ketan, oku na si ketan.

# Oro Alhadji Tafawa Balewa Ninu Ero Redio

Ojo nla ni oni yi je fun ile Nigeria, bi o si ti je wipe emi ni, eniti a koko fi je oye Prime Minister fun gbogbo ile na eyi lo fun mi nigboiya lati ba awon ara ilu mi soro. Bi mo ti ni igboiya to, bakanna ni mo tun re ara mi sile nigbati mo ba ranti ise ribiribi ati ero wiwuwo ti a gbe ka mi lori, emi ati awon isongbe mi.

Loni, a ti fi ese le ona irin ajo wa ikehin si ominira, ati nigbati yio ba fi to iwon odun meta, nigba na ni ao to ri ere ise ati ijakadi wa ti a ti njijadu lati odun de odun eyi lo jeki inu mi dun jojo lati ba nyin soro lale yi. Olukuluku wa lo ni ise lati se ninu ijakadi wa si ominira ti o mbo ni ojo keji osu April 1960. Mo fe ki enikeni ti o mbe nile Nigeria mo pe, ise na ko nse ti ebefe; ti o je wipe awon Minister Eko, ti Iwo-Orun, ti Ila-Orun ati ti Ariwa ni kan le se, ise ti o kan olukuluku wa ni, niteripe nipa ajumose gbogbo wa ni ominira ti a nfe ni 1960 yio fi te wa lowo ni otito ati ododo.



ALHADJI T. BALEWA

Awa ti so awon ohun ti a fe tabi ti a gba lero ki ominira na to te wa lowo, ni ojo keji osu April 1960, bi a ba fe wipe ki ile wa papaa je okan ninu awon orile ede agbaiye ti a ngbo oruko won, a ni lati sapa wa nitori ki nkan ti a nfe le te wa lowo pelu iyin wipe ao ni ijoba rere.

Ile Nigeria ti de aye ti gbogbo aiye nfi oju si nisisiyi, a si nilati gba ona ti a fi le wa lowo yi lati fi han gbogbo agbaiye wipe awa na ti dagba to ejubo, a to eniti o le se ijoba ara wa daradara Gbogbo omo ile Nigeria, yala ni Kiriyo, Musulumi tabi Aborisa eyikeyi to wu ki o je olukuluku ni ipin tire lati se ninu ise ti o dele yi. Mo fi eyi ke si, enyin ara ilu mi, lokunrin ati lobirin wipe, ki e jeki a jijo sowopo ki a mu ede-ko-yede kuro larin ara wa, ki a ti ola fun eniti ola ye, ki a nigbekele si ara wa, ki a si parapo fun ohun kan ti gbogbo wa nfe, ko si si ebo ti o tobi ju fun ohun ti gbogbo enia nfe.

Emi ti gbagbo, mo si fe ki enyin na gbagbo wipe ilosiwaju ile wa yi, wa lori wipe bi awa tikalara wa ba ti ran ara wa lowo si. Sugbon bi a ko ba ni emi isokan ati irepo, ko le se se. Lotito ati lododo; isokan ni a nfe larin ara wa, o si je ise fun enikeni wa lati wa ona ti isokan yio fi wa larin ara wa.

Mo ti so ni ile igbimo lowuro yi wipe bi a ba i tele ibinu ti awon oselu nda ile ko le gbe ile Nigeria de ibikan, mo si kesi gbogbo awon akonije ... ile Nigeria pe ki awa se ikilo fun awon omo egbe won.

Fun enyin Olutetisi mi lale yi mo tun so b kanna fun yin ... ki a pa oro ibinu ti sipakan ki a le fi ife gba Ominira wa.

# Oloye Tuntun De Igbajo

IGBAJO Olotu Iwe Eleti Ofe ti o wa fun agbegbe Iwo-Orun ni ona odo Oshun ni oloye tuntun de si ilu Igbajo leti Ikirun, oruko oloye na nje Adelani Famodun Odomode ni, o si ni Baba ati Iya ni aiye. Eleti Ofe ni ongbo wipe gbogbo awon omode ati agba ilu ni o wa ni ehin re.

Ni ajsi nkan, a gbo wipe Aringbajo tuntun (tabi owa Igbajo ni won npe) ao se etutu ati wo ile oye ni ijo Jimo ti o nbo yi,

Adelani, oye a pe lori o. Igbajo, e ku Ajaye Ijeba Iwo Orun e si ku agba, agba si ku iyonu

OBA ADELE SE AJODUN

Kabiyesi Alaiyeluwa Adeniji Adele Keji Oba Eko, di odun Kejo lori oye Oba Adupe ti Olorun ko pawa lekun adupe.

# Ise Owo Awon Enia Dudu



Eyi ti a nwo ninu aworan yi ni Omidan Sylvia Ribeiro ti o je omo ile Awanyin on li je okan ninu awon enia meta to duro ni ise owo awon enia dudu, Lasiko ti nwon se afihan ise owo enia dudu gbogbo nile agbaiye.

Omidan S Ribeiro lo mu opa atupa ti a fi igi se loso daradara lati ile awon enia dudu d ni. O wa silu Oyinbo fun ilosiwaju eko nipa ise ile, yio lo iwon odun merin tabi marun ki o to poda wa sile

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.
HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England

# Kile ti mo E ma Ka Iwe Irohin Eleti Ofe Ki eyi si o? E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re

Olotu,

Ọkunrin kan ara Agege lọ ra ọmọ ewurẹ kan lọdọ obinrin kan ni Ẹpẹtẹdo o si gbe ọmọ ewurẹ na lọ si ilu Agege lati ma sin.

Ewurẹ na dagba si Agege o si loyun, awọ ara ewurẹ yi lo wa ni ara iya rẹ. Awọ funfun ni ọrun ẹsẹ ọtun funfun, iru rẹ pẹlu funfun.

Nigbati ewurẹ yi to asiko ti o ni lati bimọ nṣe ni nwọn wa a ti; Nwọn wa a de abule Koka (Coker) Aboru Ayọbọ, ati Ipaja sibẹ nwọn ko ri.

Loru ọjọ kan ni Iya ti o ta ewurẹ yi ngbọ igbe ewurẹ, o si jade lati wo kini ohun ti o ṣe ewurẹ ti o nke. Iyalẹnu lo jẹ fun lati ri ewurẹ rẹ ti o nrọbi. O si fa a wọ agbole.

Nigbati ilẹ mọ, kayefi lo jẹ fun Iya elewurẹ na wipe, on mọ pe ewurẹ ti on koiti ni oyun, ewurẹ ti on lo si dure ti o nwo on yi. nibe ha ni Ewurẹ yi ti wa, ọmọ ti ewurẹ on bi ti o si jọ ọ bayi, wa ni Agege, ti ha ni ewurẹ yi.

Iya na si bẹrẹ si tọju ewurẹ na, a ko si ri ẹni kan ki o polowo pe ẹran ewurẹ ti on sọnu. Bẹ bẹ, awọn ọmọ ewurẹ di agba nwọn si ngun iya wọn.

Baba ti o ra ewurẹ lọ si Agege tun wa sọdọ iya Ẹpẹtẹdo lẹhin oṣu kẹta, lati tun wa ra ọmọ ewurẹ miran. O sọ fun iya ẹlẹran na pe eyi ti on kọkọ ra on ko ri mọ yala nwọn ji gbe tabi nwọn pajẹ.

Iya na dide kian, o si pe awọn ewurẹ rẹ jọ nigbati ọkunrin na ri ewurẹ rẹ, o mọ, o wa bere bawo lo ṣe de ihin, Iya na si rohin fun, Ha! si gbe ọmọ le wọn lọwọ.

Ọrọ yi wa di ariyanjiyan larin awọn enia, awọn ẹlomiran sọ pe nṣe ni iya yi bẹ'wẹ ki nwọn lọ mu ẹran na wa.

Ẹnyin ọkawe wa, ki ni ẹ ti mọ eyi si, lati Agege si Eko jẹ busọ mejila ati abọ. Kini ẹran na ti rin.

Jackson J. Ojo




Ohun mimu ni alẹ

-fun agbara ni gbogbo ọsan!



Ife Ovaltine kan daraju gbogbo nkan lọ ni mimu ki enia to sun. O b'ara mu o si njẹki ara sile o si nmu ni sun orun ti o gbadun. Ni ẹsẹkẹsẹ ni Ovaltine si ti nfi okun fun ọpọlọ-ori ati ara. Wa a ji dide pẹlu ara sisile, ati agbara titun, wa a si wa ni imura-sile lati yanju gbogbo nkan ti o fẹ fi ọjọ na ṣe.

*Awọn ohun ti nwọn fi ṣe Ovaltine ni ẹyin, irugbin ati wara, pẹlu nkan ti nfun ni ni agbara. Ohun mimu aladun ati onjẹ ti nfun ni ni agbara. Mu Ovaltine lale fun agbara ni gbogbo ọsan.*

OVALTINE

O JẸ ONJẸ—MIMU TI O PE TI O SI DARA PUPO




OWA.198/Y

# E L E T I Q F E

A-NJU-WQN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos    "ELETI - QFE LAGOS"

P. O. Box 467    Phone 23370

VOL. IX. NO. 540.  LAGOS, SATURDAY OCT. 5. 1957


## Jamba Oko Ile (Railway)

Agbǫjugbanu niti jamba Ọkọ Reluwe to ṣẹlẹ lọru Satide-mọju ọjọ ọsẹ tokọja nitosi Ibudo ọkọ ni Lalupọn niwaju Ibadan. Enmọ, pagidari, gudugbẹ lo ja, ti iru rẹ ko ja ri nilẹ wa nihin, paapa ti ẹmi awọn ọdọmọde ti awọn jẹ ọmọ akẹkọ nile Ẹkọ nla nilu Zaria ti awọn npada lọ s'ẹnu ẹkọ wọn ti ẹmi wọn rasu ninu iṣẹlẹ jamba ọkọ Reluwe yi.

Koṣe f'ẹnu sọ niti ibanujẹ to gbojikan lori ọkan wa fun adanu airotẹlẹ yi, adanu nla ni fun awọn obi awọn ọmọ akẹkọ na, bakanna si ni o jẹ adanu ti o tobi fun ilẹ Nigeria nitoripe awọn ni opomulero fun ilẹ wa lẹhin Ọla.

A nke ibosi wipe Ọkọ oju omi lewu pupọ, Mọto ko ṣe wọ pẹlu ifsiyabalẹ, ko si ẹniti o fẹ jafọ'lẹ lati oju Sanmọ, Ọkọ Reluwe ti a gbẹkẹle pe ororun ju ni o tun di ogun d'ẹru siju fun wa yi, eyi ha nkọ o?

Afi wosika wa yi ba awọn obi ọmọ akẹkọ ati awọn ero inu ọkọ Reluwe na kẹdun ajalu buruku yi, ki Oluwa Ọba Olodumare ki o tu wọn ninu, ki a maṣe ri iru rẹ mọ. Amin.


## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re



## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## Awon Omo Akeko Nilu Oyinbo



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ọmọ wa ti o lọ kọ ẹkọ ninu ile ẹkọ ọgbọn iṣelu ati eto asunna-owo nilu Oyinbo.

Nihin, nwọn wa jẹ onjẹ ọsan wọn lẹhin ti nwọn ti kọ ẹkọ ọjọ na pari orukọ wọn niwọnyi lati ọwọ ọtun, Ọgbẹni T. A. Otubanjọ, ọmọ wa ni, F J Meder, Jamani ni. M. Blunt, Gẹsi ni, I.F. Aiyelagbe, ọmọ wa ni, Omidan J. Yesu, ara ilẹ Trinidad ni, ati Z.O. Bibiesue, ọmọ wa ni.

Nigbati nwọn jẹun tan, nwọn mba ara wọn sọrọ.

No. 140.

## PUBLIC NOTICE

Telephone 21806    Governor-General's Office, Lagos.
September, 1957.

## The Minorities Commission

All persons, parties and organisations wishing to address the Minorities Commission are asked to notify the Secretary to the Commission of their Intention to do so. Such Notice of Intention is required to enable the Commission to plan its work in advance of its arrival in Nigeria.

2. Notices should be addressed to "The Secretary to the Minorities Commission Governor-General's Office Lagos" in writing and should include the following information:—

(1) The name and address of the person or party including where possible telephone number;

(2) Whether it is intended to address the Commission
   (a) by Memoranda or
   (b) orally or
   (c) both orally and by Memoranda;

(3) If an oral hearing is asked for the following additional information should be given:—
   [a] the names of the principal spokesmen
   [b] the place at which the person or party concerned would find it most convenient to address the Commission.

3. Such Notices of Intention should reach the Secretary not later than October 20th, 1957.

4. Where it is intended to submit memoranda to the Commission, ten Copies should be dispatched if possible to reach the Secretary by the 14th of November. This will ensure that memoranda are received before the Commssion begins to tour the Regions and will minimese the chances of their going astray.

5. The Commission which will arrive in Nigeria on the 23rd November will start its work in Lagos and will thereafter proceed to here evidence at such places as will be notified later.

(Signed) K. J. HILTON
Secretary, Minorities Commission.

# Adedoyin Jare Ejo Re



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ogbeni Adeleke Adedoyin ti o jare ejo ti o pe awon oyinbo Onisowo Jamani kan ti nwon npe ni Gaiser.

Bi a ti gbo idi ejo na si ni wipe awon onisowo Jamani nwonyi nta moto onifaji kan ni egbaa Poun, (£2000) Ogbeni Adedoyin si fi edegberin Poun lele (£800) lele wipe ki nwon gbe moto na fun on ki on ma da iyoku san, eyi owo nwon ko da pada fun on, beni nwon ko gbe moto wa.

Adedoyin so fun won pe bi nwon ko ba le gbe moto wa, ki nwon da owo pada fun on, odunrun poun £300) pere ni nwon da pada. Eyi ni ohun ti o gbe won de kotu ti adajo si da Ogbeni Adedoyin lare wipe ki o lo gba owo re to siku lowo won ki nwon si lo sanwo irin ese Poun mokandilladorun (£89) fun Ogbeni na.

# Itan Are Ona Kakanfo

Arę jẹ alagbara, o si jẹ aweja enia to gun. o si singbonlę, A ma pase nigba aiye rę, asę a si wolę, ko joye oba, sugbon o nse bi oba, Bi a ba so leti enia wipe Arę yio ku lojo kan, ko ni gbagbo, nse ni awon ara Ijaiye mberu rę, ti nwon si mbowo fun bi orisa. Igbesi aiye enikan ko jo Arę loju.

"Ori yeye ni mogun, aisę lo pọ". A ko le ka iye awon enia ti Arę ti pa danu lainidi. Ika rę pọ tobę gę ti o fi jẹ wipe, ko si

ęniti o gbodọ rubọ ki o ma sure fun Arę. Eyi na lo di ọrọ aisọ wipe Arę npe ọ, o ndifa, nję bi ifa rę ba fọ ire, ti Arę si fọ ibi ako?.

Awon opitan so wipe, gegebi Arę ti ni ika to bęsi awon omọ rę loro ninu. Ęniti o jęki ika rę pọ bę ni Balogun Ijaiye kan ti nwon npe ni Agana-Epo. Okunrin yi lo jẹ ki Arę huwa ika, nitoripe Balogun yi ni onimoran Arę. Bi o wipe ki Arę fi silę yio fi sile bi o ba si wipe pipa ni nse ni nwon o be lori.

Are ni awon eru pupo, ko si nfi won jafara. A tile ma ti han nigbati o ba lọ si Oyọ fun Jakuta; a ma sọ wipe awon eru on ko ni iya tabi baba, on nikan ni baba awon ogunlogo eru na; nitorina on ko le gba ki enikeni se won ni iwosi.

Iru oro bayi lo tumbọ jeki okan awon eru na le tobe ge ti nwon ba ba oloko ninu oko iya ajegbe ni awon ma fi je. Nigbati ote de, gbogbo awon eru na ni nwon fere pa tan nitori ika won.

Are feran awon omokunrin ile Ijaiye jojo, nitoripe ni ororun ni o ma nse ase fun won. Opo ninu awon odomokunrin Ijaiye lo ti pase ase yi so ara re di ole. Bi a ba fi oju inu wo o, ao ri wipe ejo enia ni Arę nitoripe ko nfe ri oku enia tabi oro ile tabi Iwin. Ko nfe ki a pa enia niṣoju on.

# E la oro yi ye mi?

KUMASI. Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye oro mi yi lowo enikeni ti o ba le se alaye oro na fun mi. Ibere mi na niyi :-

Nje awon baba baba wa ti nwon ti wa laiye ia koko ki awon Oyinbo to de odo wa ni ile awa enia dudu, nje oko eru ni awon baba baba wa na wa bi? Ti o ba si je wipe oko-eru ni nwon wa, tani awon ti o ra won ni eru (Slave) na? Ki e jowo, mo nfe alaye kikun.

Ajinde ara yio si ma je fun wa. Oju ko ni fara ku o.

Emi ni ti yin nitotọ

ABEREMAJEBI

c/o Y. A. Agbaje


Mo Gbadun Siga Pirate




PIRATE
Ni Siga Ti O Dara

# Alapara Ibadan Nki Yin o

OKE FỌKỌ IBADAN.

"Ifa ni ajọwo, m o n i ajọwo, tani ko mọ wipe ohun ti a ba jọwọ gigun ni gun.' Fun ẹsẹ Odu I f a ti mo fi bẹrẹ apara mi ni ọsẹ yi, m o juba gbogbo awọn Babalawo ilẹ Yoruba pataki b a b a m i Abati Atẹfa-tẹọna. Bi ekolo ba juba baba rẹ ilẹ a la ẹnu. Iba mi na a sẹ o.

Ọrọ m i dori ko dori, o di eri awọn baba wa Babalawo ilu Ibadan, ti wọn ri agbagba ki wa lọja ki eri ọmọ titun pa. W ọ n ni nitotọ a g b a ominira ṣugbon k o y e awọn si ti ilu Ibadan ko tu ti ko ba. Ẹranko ile nlọ soko, ti oko nwa sile, oru ndọsan ọsan ndoru, baba ko gbọ tọmọ, ọmọ ko gbọ ti baba. Awọn Alufa p a agbo, awọn Aladura papa nke kiri wipe "ijọba ọrun ku si dẹdẹ, ẹ paramọ. Awọn Babalawo wa m u ọp,lẹ o di ile Araba.

ALAPAPỌ OLORI EGUN IBADAN

Araba ilu Ibadan p e gbogbo awo Ibadan jọ, o ni ki wọn wa ba on tun iwa Ibadan se bi Ọrunmila se tun aiye Ifẹ se nigbati o fẹ fọ nigba Iwa ṣẹ. Odu Ogundakẹtẹ lo jade fun ilu Oluyọle nibi ole g b e njare o n i n k a n. Ijọ ba ti sọ aiye dẹrọ.

A w e njẹ o mọ wipe egungun kan wa ni 'Badan ti o ju Ololu, Atipakọ, Aiyelabọla ati Alapansanpa lọ.

Nigbati mo nṣe sanmọri ọjẹ Alapasanpa ni mo nko atori tẹle lẹhin nko mọ wipe egungun kan wa ti wọn npe ni ALAPAPỌ. Alapapọ ni egungun akọkọ si Ibadan on ni Ọrunmila Agbọnniregun ni ko gbẹ ebọ ti o yọ si Ibadan. Ẹnyin Babalawo ẹ gba wa o. Ẹbọ yio da o; bawa tun ilu ṣe o. Ki ominira ti a gba yi ko san wa jake jado. Abọru, abọye o, abọye-bọsẹ.

APEJỌ ẸGBẸ BABALAWO

Wọn ni Ọlọya ki jẹ agbo. Alapara mo ṣe ojunto. Mo ṣe ojun'o titi de Ile Ila ninu oṣu Ọwẹwẹ ti a ''a yi – September ni ẹyin ọmọ Oloyinbo npe. Ire ti o sọnu ni mo wa lọ mo si mu irẹ na bọ. Di Alapara ti de Ile Ila ti mo nfẹ ṣe ofin toto diẹ ni awujọ awọn Babalawo ti wọn nṣe ajọ-nla, apejọ-ilupe, Konfrẹnsi tabi Konfẹnsọn ni adapọ ede ti ẹ npe? Ajọ awọn baba ṣoro, were ti mo ti mo ti debẹ ni wọn ni irẹ nrun, irẹ nrun. A jẹ bọmọde ba mọ wọ wẹ; a mọ ba agba jẹun? Alapara mọ ọwọ wẹ mo si nba agba jẹ. Ijọ keji ti mo ra pala lati ba wọn to aga apejọ bi iṣẹ ọmọ ilu Ila ni mo ri awọn aje Awo ni apejọ na. Awọn jakanjakan bi Aberefa lati Ikire, Alagba Awofinsa, Okunọ l a Ojugbọna Ibadan, Awofinṣa, Alagba Oriṣọna Oyekomi, Aremu Ojugbọna Ilọrin, Adeboun Ojugbọna Ẹgba, Faboya lati Ikole, Afuape lati Ishara ọmọ Afọta modi, Abimbọla ati Shonibare lati ilu Eko, Adenuga lati Ijebu-Ode, Ọgbẹni akọwe Dosunmu ati igba keji re G. A. Ọdunade (igbakeji akowe.) Wọn le ni egberun ti o pe si apejọ na. Awe, ọrọ pọ nibe, ṣugbọn wọn ni ki nmọ ka beni ẹmi Alapara emi Alapara k o le ri ki nma sọ; ṣugbọn baba mi, ọmọ Abati Atẹfa-tẹọna ti kilọ fun mi pe gbogbo a ṣ ọ kọ ni a nsa lorun, ọrun rere o, Ọmọbọlaji.

A w e , a jẹ awọn baba wa ko kẹrẹ n i n u eto. Alapara Ibadan ko le ri ki o mọ sọ, ipade ti gbogbo enia nwọ wa lo bọ si ilu Ọyọ. Ọba Gbadegẹsin Ladigbolu Keji, ẹ ku ipalẹmọ a l e j o . Ni a g b a r a Olodumare emi Alapara Ibadan ni ma kọ de Atiba ti ma lugọ d e yin. Rere yin ni mo nfẹ o, ẹnyin baba mi. Ṣugbọn nigbawo ni E k o ni ki ẹ wa ? Iyoku dọwọ rẹ Eko Akete I l e Ọgbọn. Ninu oṣu Opẹpẹ (n i n u Ọ y ẹ Keresimesi) ni mo nlọ si Ọyọ. Alapara nki yin o.

# Asayan Oro Inu Alukurani Mimo

1. Awọn ẹnirere mbẹ larin awa enia aiye isisiyi, bẹni awọn ẹni buburu wa pupọ. Ṣugbọn ọna olukuluku yatọ si ara wọn.
2. Awọn alaimọkan enia a ma sọ wipe Ọlọrun ni iyawo; ati pe o bimọ. Ko nṣe ohun ẹtọ fun awọn enia tabi Alijannu, lati ma sọ isọkusọ si Olodumare.
3. Bi o tilẹ jẹ wipe awọn ogboju ninu awọn enia nwa isọri lọdọ awọn ogboju ninu awọn alijannu eyi ko din kinkinni ku ninu ẹsẹ ti enia ti ṣẹ.
4. Ọlọrun ọba lo ṣe ẹda enia lati inu omi ara si ara, lati ibadi ọkunrin si ọrun obinrin. Njẹ ẹniti o ṣe iru eyi, yio ha tun ṣoro fun lati ṣe ayipada enia lẹhin ti oluwa rẹ ba ku tan?
5. Eyi ni awọn e n i a buruku, ti a o gbe ju si na ina, fun ere iṣẹ wọn. Nwọn o gbe inu ina Janọmọ fan ọdun gbese, ẹfufu ko ni de ọdẹ wọn, a yafi oru gbinbona ati omi gbigbona, eyi ni ere iṣẹ wọn, ojiji ni iparun na yio de ba wọn nitoripe, nwọn ko ni mimọ pe, nwọn o jihin iṣẹ ti wọn ṣe.


## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun German to şeşe de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.



## CARSON PAINTS AND VARNISHES




SOLE AGENT:—
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, BALOGUN STREET, LAGOS

No. 73/S.2/Vol. VIII/524

# Western Region Public Service

## Office Of The Commissioner For The Western Region In The United Kingdom

Applications are invited from suitably qualified Nigerian of Western Region Origin for appointment to fill the following post in the Public Service of the Western Region of Nigeria:

| Designation | No. of Vacancies |
|---|---|
| Assistant Students' Welfare Officer | one |

Salary Scale: C(E) 1, 2 (i.e.) £390 x 18 - 444 x 24-492 £540 x £24-588; £660 x 24-684 x 30 - 714).

For full details and methods of application please see Western Region of Nigeria Gazette No. 45 Vol. 6 Notice No. 874 of 19/9/57.

Closing Date:
Overseas Candidates 27/9/57
All other Candidates 4/9/57.

No. 73/S.2/Vol. VIII/524.

# Education Department Western Region

## VACANCY FOR TECHNICAL INSTRUCTOR, TRADE TRAINING CENTRE

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Technical Instructor in a Trade Training Centre, Education Department, Western Region.

2. Salary Scale - C(T) 2,3,4: £570 x 24-744; £774 x 30 - 864; £900 x 36 - 972; £1,014.

For full details and method of application please see Gazette No. 45 Vol. 6 Notice No 877 of 19th September, 1957.

Closing date: Overseas Candidates 3/10/57
All other Candidates 10/10/57

## E Ma Gba Ni Ke, Ewo Ni Jamba Oko Ewe !

**Olorun ko ma gba wa lodun ni, oko Reluwe kan lo ye loju irin ti o si se oniko iku opo enia, ni a ri ti a nwi, Oko miran lo tun ja lule ninu ose yi l'Oshogbo. Olorun ko ma gbawa lodun ni.**

# Imoran rere fun gbogbo Enia

Dajudaju bi kidirin inu ba nsise daradara lo nmu alafia ba ara enia. Bi kidirin inu re ko ba sise deedee tabi amodi nyo o lenu n pa aiko sise deedee kidirin re -- aisan bi Ehin-didun, Lakuregbe, ara riro l'orikerike, Iseto ati awon aisan bawonnii- gba o ni imoran ki o lo egbogi yi-

## Pilules V. E. Doumer

Egbogi ajebidan fun aisan kidirin yi je ti awon Faranse Ojulowo kosemani ninu ile ni fun gbogbo ebi.

Sile meta (3/-) pere ni. Fi owo oko si.

**French Medicine Stores,**

18, Breadfruit Street, Lagos. Phone 23264.

# Jamba Se 'Oko-Ile



**Irohin ti o gbojikan kakiri agbaiye ninu ose yi niti Reluwe, Oko Ero kan ti o nlo si Kano ti jamba sele si, ni arin meji irin ajo re. Iru Ero oko Reluwe ti a nwe yi, to je wipe, on lo nfa oko ero na sure, je okan ninu awon ero ti o baje petu wagonu nibiti awon ero oko njoko si. A gbo wipe iye awon enia to ku sidi jamba oko na lo ni ni igba, ati wipe awon odomode ti o nlo bere eko won nilu Zaria lo ku Pupoju.**

**Lowo iku gbigbona ati iku ojiji, Oluwa rere gbawa.**

## ANFE ASOJU

A nfe Asoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Ofe lati fi kun awon Asoju wa si awon ilu ti a daruko si isale wonyi:-

Abeokuta, Ijebu-Ode, Ijebu-Igbo, Ile-Ife, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kowe si Olotu Iwe Irohin Eleti Ofe, 28, Kosoko St, Lagos.


## Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials

PLEASE CONSULT:

# Okunowo Brothers

63 Massey Street, (Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The house where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

# M.B.T.
(MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn paradà. M.B.T. dé, òkùnrùn fò lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú sáré. ojú pòṣèṣè. Àlá buburú wọ'gbó. àìlèsùn r'ẹ̀hìn-ẹ̀kùn. M.B.T. l'ògùn-ẹ̀jẹ̀ ti nmú ni jẹun b'íkan, amú ni yàgbẹ́ bi ọ̀kùn, amú ni tọ̀ bi àkèré. Abíwẹ́rẹ́ f'áboyún, agbẹ̀jẹ̀ di fawọn abiyamọ. Ahọ́n-dúdú, ẹ̀sẹ̀-wíwú ati àìyà-jíjá ko ṣi pẹ́nìtí nlo o.

4/6d pẹ̀lú 1/6d owó-ọkọ̀.

ARADAN STORES P.O. Box 2 EBUTE-METTA.


No. 73/S.2/529

## Printing and Stationery Department
### Vacancy For Typewriter Mechanics.

Applicants are invited from suitably qualified candidates, who possess a minimum educational qualification or Class IV Middle, for appointment in the Printing and Stationery Department, Western Region, Ibadan, as Typewritery Machanic, Preference will be given to men with previous recognised experience with a large organisation. Particulars of the vacancies-

Vacant Office - Typewriter Machanic

Salary : Scale F. 1,2,3: £114 x 6 - 156; £165 x 9 - 204; £216 x 12 - 276.

For further particulars and method of application please see Gazette No 46 Vol 6 Notice 918 of 26/9/57.

Closing Date: 31/10/57

# Oloye E. A. Fadayiro



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye E. A. A. Fadayiro, ti o nṣe akọwe ilu, on ni ẹniti o lọ ṣi ile iwosan ti a fi ẹgbẹrin Poun kọ si ilu Oke Ọdan.

Ni Ifọnyin-tẹdo ni nwọn kọ ile iwosan na si. Omidan K. I. Cole ni Olutọju ilera ilu Dokita, Ọtọlorin ti o m'ẹ fun agbegbe ilẹ Ẹgbado lo wa fun Oke-Ọdan.

No.73/S.2/529

## Printing and Stationery Department
### Vacancies for Printer, Grade III

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment in the Printing and Stationery Department, Western Region, Ibadan as Printer Grade III.

Salary: Scale E 1B, C.3: £150 x 9 - 168 x 27 £195 x 9 - 240; £252 x 12 - 300; £315 x 15 - 360.

Qualifications Required: Class VI or Cambridge School Certificate, or West Africa School Certificate or G. C. E. Ordinary level with a pass in at least 3 subjects and should have an interest in being trained in technical subjects appertaining to the Printing Trade.

For further particulars and method of application please see Gazette No. 46 Vol. 6 Notice No. 919 of 26/9/57.

Closing Date: 31/10/57,

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re


## Ere Esin
### RACE! RACE! RACE!
### Ti Eko, Abeokuta ati Ibadan.

Ti race bade, ti irẹ ko bi Ilọ ṣa ranṣẹ wa ba wa pẹlu nọmba ẹṣin ti ofẹ lati ra

Kofi Ṣile Marun Pere Ranṣẹ (5/-)

Awa Yio Ra Ẹṣin Rẹ Fun Ẹ,

Iwọ yio si gba owo ti wọn ba pin lori ẹṣin na ni Ọdan

Ranṣẹ Si:-

WILLIAMS SYNDICATE
51A, PALM CHURCH ST.
LAGOS.



## Lati fun o lokun-inu ati agbara re pada

Lẹhin

AMODI INFLUENSA

lo egbogi

### Hommel's Haematogen

pẹlu Wara tabi Ọti Waini fun ọsẹ kan tabi meji

A le rira ni Ṣọbu ti nwọn nta egbogi ati ni gbogbo ile itaja

ALAKOSO EGBOGI NA NI:-

ALBAN PHARMACY LTD.
2, VICTORIA STREET,
Lagos.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street P. Box 467 Lagos Phone 2557